48

# AWỌN ARA GALATIA.

**(A.D. 58)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni Paulu.**

PAULU, Aposteli ki i ṣe lati ọdọ ènìyàn wá, tabi nipa eniyan, ṣugbọn nipa Jesu Kristi, ati Ọlọrun Baba, ẹni ti o ji dide kuro ninu òkú. (2 Kor 1:1; ẹsẹ 11,12; A.A. 9:6; 2:24.)

2. Ati gbogbo awọn arakunrin ti o wà pẹlu mi, si àwọn ìjọ Galatia: (Filp 4:21; 1 Kor 16:1.)

3. Oore-ọfẹ si yin ati alaafia lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Jesu Kristi Oluwa wa. (Rom 1:7.)

4. Ẹni ti o fi oun tikararẹ̀ fun ẹ̀ṣẹ̀ wa, ki o lè gbà wa kuro ninu ayé buburu isinsinyìí, gẹgẹ bi ifẹ Ọlọrun ati Baba wa: (Rom 4:25; Gal 2:20; 2 Kor 4:4.)

5. Ẹni ti ogo wà fun lae ati laelae. Amin. (Rom 16:27.)

**Ìdí ti Paulu fi kọwe.**

6. Ẹnu yà mi nitori ti ẹ tètè kuro lọdọ ẹni ti o pè yin sinu oore-ọfẹ Kristi, si ihinrere miran: (Gal 5:8; 2 Kor 11:4.)

7. Èyí ti ki i ṣe omiran; bi o tilẹ ṣe pé awọn kan wà rí ti nyọ yin lẹnu, ti wọn si nfẹ yí ihinrere Kristi padà. (A.A. 15:24; Gal 5:10.)

8. Ṣugbọn bi o ṣe awa ni, tabi angeli kan lati ọrun wá, ni o bá wàásù ihinrere miran fun yín ju eyi ti a ti wàásù fun yín lọ, jẹ ki o di ẹni ìfibú. (2 Kor 11:4,14; Rom 9:3.)

9. Bi awa ti wi ṣaaju, bẹẹ ni mo si tun wi nisinsinyìí pe, Bi ẹnikan bá waasu ihinrere miran fun yin ju eyi tí ẹyin ti gbà lọ, jẹ ki o di ẹni ìfibú. (Rom 16:17.)

10. Njẹ ni isinisnyìí eniyan ni emi nwá ojurerere rẹ̀ ni tabi Ọlọrun? Tabi eniyan ni emi nfẹ lati wù bi? Bi nbá nfẹ lati wu eniyan, emi kò lè jẹ́ iranṣẹ Kristi (1 Tess 2:4.)

**Paulu Aposteli nipa ore-ọfẹ Ọlọrun.**

11. Ṣugbọn, ará mo fẹ ki ẹ mọ pe ihinrere ti o mo ti waasu ki i ṣe nipa ti eniyan. (1 Kor 15:11.)

12. Nitori ki i ṣe lọwọ ènìyàn ni mo ti gba a, bẹẹ ni a kò fi kọ́ mi, ṣugbọn nipa ifihan Jesu Kristi. (ẹsẹ 1,16; Ef 3:3.)

13. Nitori ẹ̀yin ti gburo ìwà-ayé mi nigba atijọ ninu ìsìn awọn Ju, bi mo ti ṣe inunibini si ìjọ eniyan Ọlọrun rekọja ààlà, ti mo si ba a jẹ: (A.A. 8:3; 9:21.)

14. Mo si ta ọpọlọpọ awọn ẹlẹgbẹ́ mi yọ ninu ìsìn awọn Ju laarin awọn ara ilú mi, mo si ni ìtara lọpọlọpọ si òfin atọwọdọwọ awọn baba mi. (A.A. 22:3; Kol 2:8.)

15. Ṣugbọn nigba ti o wu Ọlọrun, ẹni ti o yà mí sọ́tọ̀ lati inu ìyá mi wá, ti o si pè mi nipa oore-ọ̀fẹ́ rẹ̀. (Isa 49:1,5; Jer 1:5; A.A. 9:15; Rom 1:1.)

16. Lati fi Ọmọ rẹ̀ hàn ninu mi, ki emi lè maa wàásù rẹ̀ laarin awọn Keferi; lojukannaa emi ko ba ara ati ẹ̀jẹ́ gbìmọ̀ pọ̀: (A.A. 9:20; Ef 6:12.)

17. Bẹẹ ni emi kò goke lọ si Jerusalẹmu tọ awọn ti i ṣe Aposteli ṣaaju mi: ṣugbọn mo lọ si Arabia, mo sì tun pada wá si Damasku.

**Ìjọ Ọlọrun paapa gba Paulu gẹgẹ bi Aposteli.**

18. Lẹhin ọdun mẹta, nigba naa ni mo gòkè lọ si Jerusalemu lati lọ ki Peteru, mo si gbe ọdọ rẹ̀ ni ijọ mẹẹdogun, (A.A. 9:22,23,26,27.)

19. Ṣugbọn emi kò ri ẹlomiran ninu awọn Aposteli miran, bikoṣe Jemisi arakunrin Oluwa. (Matt 13:55.)

20. Nkan ti emi nkọwe si yin yìí, kiyesi i, niwaju Ọlọrun emi kò ṣèké.

21. Lẹhin naa mo sì wa si àgbègbè Siria ati ti Kilikaia; (A.A. 9:30.)

22. Mo si jẹ ẹni ti a kò mọ̀ lójú fun awọn ijọ ti o wà ninu Kristi ni Judea: (1 Tess 2:14; Rom 16,7.)

23. Ṣugbọn kìkì wọn ti gbọ́ pé, "Ẹni ti o ti nṣe inunibini si wa rí, ti nwaasu igbagbọ naa ti o ti nbàjẹ́ nigbakan rí ni isinsinyìí."

24. Wọn si yin Ọlọrun logo nitori mi.

ORI 2.

**Awọn Aposteli iyoku gba Paulu gẹgẹ bi Aposteli.**

LẸHIN ọdun mẹrinla, nigba naa ni mo tun gòkè lọ si Jerusalẹmu pẹlu Barnaba, mo sì mú Titu lọ pẹlu mi. (A.A. 15:2.)

2. Mo si goke lọ nipa ifihàn, mo gbe ihinrere naa ti mo nwaasu laarin awọn keferi kalẹ̀ niwaju wọn, (ṣugbọn níkọ̀kọ̀ fun awọn ti o jẹ ẹni nla) ki o má baa jẹ pe mo nsare tabi mo ti sare lásán ni. (A.A. 15:12; Gal 1,6; Filp 2:16.)

3. Ṣugbọn a kò fi agbara mu Titu ti o wà pẹlu mi, ẹni ti i ṣe ara Griki lati kọlà. (2 Kor 2:13; A.A. 16:3; 1 Kor 9:21.)

4. Ati nitori awọn èké arakunrin ti a yọ́ mu wọ inú wa wá, awọn ẹni tí ó yọ́ wa ṣe amí lati ri ominira wa, ti awa ni ninu Kristi Jesu, ki wọn lè mu wa wá sinu ìdè; (A.A. 15:1; 2 Kor 11:26.)

5. Fun wọn, a kò tilẹ̀ fi ààyè silẹ̀, nigba kan rárá; ki otitọ ihinrere lè maa wà titi pẹlu yin. (ẹsẹ 14; Kol 1:5.)

6. Ṣugbọn niti awọn ti o dabi ẹni nla, (ohunkohun ti o wù ki wọn jásí, kò jẹ nkankan fun mi: Ọlọrun kò ṣe ojusaju ẹnikẹni:) ani awọn ti o dabi ẹni-nla, kò kọ́ mi ni nkankan. (Gal 6:3; Rom 2:11; 2 Kor 12:11.)

7. Ṣugbọn kàkà bẹẹ, nigba ti wọn rii pe a ti fi ihinrere ti awọn alaikọlà le mi lọ́wọ́, bi a ti fi ihinrere ti awọn onílà le Peteru lọ́wọ́ (1 Tess 2:4; A.A. 13:46.)

8. (Nitori ẹni ti o ṣiṣẹ́ ninu Peteru si iṣẹ Aposteli ti ìkọlà, oun kannaa ni ó ṣiṣẹ ninu mi fun awọn Keferi pẹlu.)

9. Ati nigba ti Jemisi , ati Kefa, ati Johanu, awọn ẹni ti o dabi ọ̀wọ̀n, wòye oore-ọfẹ ti a fifun mi, wọn si fi ọwọ́ ọ̀tún ìdàpọ̀ fun emi ati Barnaba, pe ki awa naa lọ sọdọ awọn Keferi, ati awọn sọdọ awọn onílà. (Rom 12:3; Gal 1:16.)

10. Kìkì wọ́n fẹ́ ki a maa ranti awọn tálákà, ohun kannaa gan ti mo nfi titaratitara ṣe pẹlu. (A.A. 11:29,30; 24:17.)

**Paulu bá Peteru wí gẹgẹ bi Aposteli ẹlẹgbẹ rẹ̀.**

11. Ṣugbọn nigba ti Peteru wa si Antioku, mo ta kò ó loju ara rẹ̀, nitori ti o jẹ ẹni tí à bá bawi. (A.A. 11:10.)

12. Nitori pe ki awọn kan ti o ti ọ̀dọ̀ Jemisi wa tó dé, o ti nba awọn Keferi jẹun: ṣugbọn nigba ti wọn de, o fà sẹhìn, o si ya ara rẹ̀ sọtọ, o bẹ̀rù awọn ti ikọlà.

13. Awọn Ju ti o kù jumọ ṣe àgàbàgebè bẹẹ gẹgẹ pẹlu rẹ̀; tobẹẹ ti wọn si fi àgàbàgebè wọn fa Barnaba tikararẹ lọ. (ẹsẹ 1.)

14. Ṣugbọn nigba ti mo rii pe wọn kò rìn deedee gẹgẹ bi otítọ́ ihinrere, mo wi fun Peteru niwaju gbogbo wọn pe, Bi iwọ, tii ṣe Ju ba nrìn gẹgẹ bi ìwà awọn Keferi, laisi awọn Ju, eeṣe ti iwọ fi nfi agbara mu awọn Keferi lati maa rìn bi awọn Ju? (ẹsẹ 5,9,11.)

15. Awa ti i ṣe Ju nipa adanidá,ti ki i sii ṣe Keferi ẹlẹ́ṣẹ̀, (Filp 3:4,5; Matt 9:11.)

16. Ti a mọ pe a kò dá ẹnikẹni láre nipa iṣe ofin, bikoṣe nipa igbagbọ ninu Jesu Kristi, ani awa naa gba Jesu Kristi gbọ́, ki a baa lè dá wa lare nipa igbagbọ ti Kristi, kii si i ṣe nipa iṣẹ́ òfin: nitori pe nipa iṣẹ́ òfin kò si eniyan kan ti a o dáláre. (A.A. 13:39; Rom 1:17; 3:20.)

17. Ṣugbọn nigba ti awa ba nwa ọ̀nà lati ri ìdáláre nipa Kristi, bi a ba ri àwa tikarawa ni ẹlẹ́ṣẹ̀, njẹ Kristi ha nṣe iranṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ bi? Ki a má rii. (ẹsẹ 15; Gal 3:21.)

18. Nitori pe bi mo ba sì tún gbe awọn ohun ti mo ti wó palẹ ró, mo fi ara mi hàn bi arúfin.

19. Nitori pe nipa ofin mo ti di òkú si ofin, ki emi lè wà láàyè si Ọlọrun. (Rom 8:2; 6:14; 2 Kor 6:15; 1 Tess 5:10.)

20. A ti kàn mi mọ agbelebu pẹlu Kristi, ṣugbọn mo wà láàyè, sibẹ ki i ṣe emi mọ́, ṣugbọn Kristi, wà láàyè ninu mi; wíwà ti mo sì wà láàyè ninu ara, mo wà láàyè ninu igbagbọ Ọmọ Ọlọrun, ẹni ti o fẹ mi, ti o si fi oun ti-kararẹ fun mi. (1 Pet 4:2; Ef 5:2; Tit 2:14.)

21. Emi kò sọ oore-ọfẹ Ọlọrun di asán: nitori pe bi ododo ba ti ipa òfin wá, njẹ Kristi kú lásán. (Gal 3:21.)

## ORI 3

**Itanjẹ awọn ara Galatia.**

EYIN aláìnírònú ará Galatia, tani ha tàn yín jẹ, ki ẹyin máṣe gba otitọ gbọ́, loju ẹni ti a fi Jesu Kristi hàn gbangba laarin yín ni ẹni ti a kàn mọ́ agbelebu. (Gal 1:2; 5:7; 1 Kor 1:23.)

2. Kìkì eyi ni mo fẹ bèèrè lọwọ yin: Nipa iṣẹ́ òfin ni ẹ̀yin gba Ẹmí bi, tabi nipa igbọran pẹlu igbagbọ? (A.A. 2:38; Rom 10:16,17.)

3. Bayìí ni ẹyin ṣe gọ̀ tó bí? Ẹyin ti o bẹ̀rẹ̀ nipa ti Ẹmi, a há ṣe yín pé ni isinsinyìí nipa ti ara? (Gal 4:9; Heb 7:16.)

4. Ẹyin ha ti jìyà ọpọlọpọ nkan wọnyìí lásán? Bi o ba ṣe pe nitootọ́ lásán ni. (1 Kor 15:2.)

5. Nitori naa ẹni ti o fun yin ni Ẹmí naa, ti o si ṣe iṣẹ-agbara laarin yin, nipa iṣẹ ofin ni o fi nṣe e ni, tabi nipa igbọran pẹlu igbagbọ? (Filp 1:19; 1 Kor 12:10; Rom 10:17.)

**Paulu jẹri si igbagbọ Abrahamu.**

6. "Gẹgẹ bi Abrahamu ti gba Ọlọrun gbọ́, a si kà a sí fun un ni ododo." (Gen 15:16; Rom 4:3; Jms 2:23.)

7. Nitori naa ki ẹ̀yín mọ̀ pe awọn ti i ṣe ti igbagbọ, awọn naa nii ṣe ọmọ Abrahamu. (ẹsẹ 9.)

8. Bi ìwé-mimọ sì ti ri i tẹlẹ pe, Ọlọrun yoo da Keferi láre nipa igbagbọ, o ti waasu ihinrere ṣaaju fun Abrahamu, o nwi pe, "Ninu rẹ ni a o bukun fun gbogbo orilẹ-èdè." (Gen 12:3; A.A. 3:25.)

9. Gẹgẹ bẹẹ ni awọn ti i ṣe ti igbagbọ jẹ ẹni alabukun-fun pẹlu Abrahamu olódodo. (Rom 4:16; ẹsẹ 7.)

**Igbagbọ laisi Iṣẹ́.**

10. Nitori pe iye awọn ti nbẹ ni ipa iṣẹ́ ofin nbẹ labẹ ègún: nitori ti a ti kọ ọ pe, "Ìfibú ni olukuluku ẹni tí kò duro ninu ohun gbogbo ti a kọ sinu ìwé ofin lati maa ṣe wọn." (Deut 27:26.)

11. Nitori o daniloju pe, a kò dá ẹnikẹni lare niwaju Ọlọrun nipa iṣẹ ofin: nitori pe, olódodo yoo yè nipa igbagbọ." (Gal 2:16; Hab 2:4; Heb 10:38.)

12. Ofin kii si i ṣe ti igbagbọ: ṣugbọn "Ẹnikẹni ti nṣe e yoo yè nipasẹ wọn." (Lef 18:5; Rom 10:5.)

13. Kristi ti rà wá padà kuro lọwọ ègún òfin, ẹni ti a fi ṣe ègún fun wa: nitori ti a ti kọ ọ pe, "Ifibu ni olukuluku ẹni ti a fi kọ́ sori igi (Gal 4:5; A.A. 5:30; Deut 21:23.)

14. Ki ibukun Abrahamu baa lè wá sori awọn Keferi nipa Kristi Jesu; ki awa baa lè gba ìlérí Ẹmí nipa igbagbọ. (Rom 4:9; Joel 2:28; 13:14.)

**Majẹmu tí Ọlọrun ba Abrahamu dá.**

15. Ara, emi nsọrọ bi ènìyàn: bi o tilẹ jẹ pe majẹmu eniyan ni, ṣugbọn bi a ti fi ìdí rẹ mulẹ̀, kò si ẹni ti o lè sọ ọ di asán, tabi ti o lè fi kun un mọ́. (Heb 9:17.)

16. Njẹ fun Abrahamu ati fun irú-ọmọ rẹ̀ ni a ti ṣe awọn ileri naa. Oun kò wi pe, "Ati fún iru-ọmọ rẹ̀", eyi ti i ṣe Kristi. (Gen 12:3; 13:15; A.A. 3:25.)

17. Eyi ti mò nwí ni pe: majẹmu ti Ọlọrun ti fi idi rẹ̀ múlẹ̀ niṣaaju, ofin ti o dé lẹhìn ọgbọ̀n-lé-nirinwo ọdún kò lè sọ ọ di asán,ti à bá fi mu ìlérí naa di alailagbara. (Eks 12:40; Rom 4:13.)

18. Nitori bi ìjogún naa ba ṣe ti ofin, ki i ṣe ti ileri mọ́: ṣugbọn Ọlọrun ti fi i fun Abrahamu nipa ileri. (Rom 4:14; 8:17.)

**Agbara ti ofin.**

19. Nje ki ha ni òfin? a fi kun un nitori irekọja tití irú-ọmọ ti a ti ṣe ileri fun yoo fi de; a sì tipasẹ awọn angeli lànà rẹ̀ lati ọwọ alárinà kan wá. (A.A. 7:53; Deut 5:5.)

20. Njẹ alárinà bi laarin ẹgbẹ́ ti o ju ọkanṣoṣo lọ; ṣugbọn ọkan ni Ọlọrun. (Heb 8:6.)

21. Nitori naa ofin ha lodi si awọn ileri Ọlọrun bí? Ki a má rii; Nitori ibaṣe pe a ti fi ofin kan fún ni ti o lagbara lati sọni di ààyè nitootọ, ododo ìbá ti tipasẹ ofin wà. (Gal 2:17,21.)

22. Ṣugbọn iwe-mimọ ti sé gbogbo nkan mọ́ sabẹ ẹ̀ṣẹ̀, ki a lè fi ileri nipa igbagbọ ninu Jesu Kristi fún awọn ti o gbàgbọ́,

**Igbagbọ bori ofin.**

23. Ṣugbọn ki igbagbọ tó dé, a ti pa wá mọ́ labẹ ofin, a si sé wa mọ́ de igbagbọ ti a nbọwa fihàn. (Rom 11:32.)

24. Nitori naa ofin ti jẹ olukọni lati mú ni wá sọdọ Kristi, ki a lè dá wa láre nipa igbagbọ. (Rom 10:4; 1 Kor 4:15; Gal 2:16.)

25. Ṣugbọn lẹhin ìgbà ti igbagbọ ti dé, awa kò sí labẹ olukọni mọ́.

26. Nitori pe ọmọ Ọlọrun ni gbogbo yin, nipa igbagbọ ninu Kristi Jesu (Jhn 1:12; Rom 8:14.)

27. Nitori pe iye ẹ̀yin ti a ti baptisi sinu Kristi, ti gbe Kristi wọ̀ (Rom 6:3; 13:14.)

28. Kò le sí Ju tabi Griki, ẹrú tabi ominira, ọkunrin tabi obinrin nitori pe ọkan ni gbogbo yin jẹ ninu Kristi Jesu. (Kol 3:11; Jhn 10:16; Ef 2:14,15.)

29. Bi ẹyin ba si jẹ ti Kristi, njẹ ẹyin ni irú-ọmọ Abrahamu, ati arole gẹgẹ bi ileri. (1 Kor 3:23; Gal 4:28.)

ORI 4.

NJẸ ohun ti mo nwi ni pe, niwọn igba ti àrólé naa bá wà ni èwe, kò yatọ ninu ohunkohun si ẹrú bi o tilẹ̀ jẹ́ oluwa ohun gbogbo.

2. Ṣugbọn o wà labẹ olutọju ati ìríjú titi àkókò ti baba ti yàn tẹ́lẹ̀.

3. Gẹgẹ bẹẹ si ni awa, nigba ti awa wà ni èwe, awa wà ni òndè labẹ ipilẹṣẹ ẹ̀dá: (Kol 2:8,20; Heb 5:12.)

4. Ṣugbọn nigba ti akókò kikun naa dé, Ọlọrun rán Ọmọ rẹ̀ jade wa, ẹni ti a bi ninu obirin ti a bi labẹ ofin. (Ef 1:10; Matt 5:17.)

5. Lati ra awọn ti nbẹ labẹ ofin padà, ki awa lè gba ìsọdọmọ, (Ef 1:7; Jhn 1:12; Ef 1:5.)

6. Ati nitori ti ẹyin jẹ ọmọ, Ọlọrun si ti rán Ẹmi Ọmọ rẹ̀ wá sinu ọkàn yín, ti nke pe, "Abba, Baba". (Rom 5:5; 8:15.)

7. Nitori naa iwọ ki i ṣe ẹrú, bikoṣe ọmọ; ati bi iwọ ba nṣe ọmọ, njẹ iwọ di àrólé Ọlọrun nipasẹ Kristi.

**Ẹ maṣe pada sóko ẹrú mọ́.**

8. Tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀, nigba ti ẹyin koì ti mọ Ọlọrun, ẹyin ti sìnrú fun awọn ti ki i ṣe Ọlọrun nipa ẹ̀dá. (Ef 2:12; 1 Tess 4:5; 1 Kor 12:2.)

9. Ṣugbọn nisinsinyìí, nigba ti ẹyin ti mọ Ọlọrun tán tabi ki a sa kúkú wi pe, ẹ di mímọ̀ fun Ọlọrun, èéhà ti rí ti ẹ tun fi yipada si alailera ati alágbe ipilẹṣẹ ẹ̀dá, labẹ eyi ti ẹ̀yin tun fẹ́ pada wá sìnrú? (1 Kor 8:3; Kol 2:20.)

10. Ẹyin nkiyesi ọjọ, ati akoko, ati ọdun. (Rom 14:5.)

11. Ẹ̀rù yin nbà mí, ki o má bà ṣe pe lásán ni mo ṣe làálàá lori yin. (1 Tess 3:5.)

12. Ará, mo bẹ̀ yin, ẹ dà bí emi; nitori emi dà bí ẹyin: ẹyin kò ṣe mi ni ibi kan. (Gal 6:18.)

13. Ẹyin mọ̀ pé ninu ailera ni mo waasu ihinrere fun yin ni àkọ́kọ́. (1 Kor 2:3.)

14. Eyi ti o sì jẹ ìdánwó fun yin ní ara mi ni ẹ kò kẹ́gàn, bẹẹ ni ẹ kò si kọ̀; ṣugbọn ẹ̀yín gbà mi bi angeli Ọlọrun, ani bi Kristi Jesu. (Matt 10:40; Luk 10:16.2 Kor 12:7.)

15. Njẹ ayọ̀ yin igba naa há dà? Nitori mo gba ẹ̀rí yin jẹ́ pe, iba ṣeeṣe, ẹ̀

bá yọ oju yin jade, ẹ̀ bá si fi wọn fun
mi.
16. Nję mo ha di ọ̀tá yin nitori mo
sọ otitọ́ fun yin bí? (Amos 5:10.)
17. Wọn nfi itara wa yin, ṣugbọn ki i
ṣe fun rere; wọn nfẹ ja yin kuro, ki
ẹyin lè maa wá wọn.
18. Ṣugbọn o dara lati maa fi itara
wá ni fun rere nigbagbogbo, ki i sii ṣe
nigba ti mo wà pẹlu yin nikan. (ẹsẹ
5,14.)
19. Ẹyin ọmọ mi kékèké, ẹyin ti mo
tun nrọbi títí a o fi ṣe ẹ̀dá Kristi ninu
yin. (1 Jhn 2:1; 1 Kor 4:15; Ef 4:13.)
20. Iba wu mi lati wà lọdọ yin nisin-
sinyií, ki emi si yi ohùn mi pada nitori
pe mo dààmú nitori yin.
21. Ẹ wi fun mi, ẹyin ti nfẹ wà labẹ
ofin, ẹ ko ha gbọ́ ofin (Luk 16:29.)
22. Nitori a ti kọ ọ pe, Abrahamu ní
ọmọ ọkunrin meji, ọkan lati ọdọ ẹrú-
binrin, ati ọkan lati ọdọ̀ ominira obin-
rin. (Gen 16:15; 21:2,9.)
23. Ṣugbọn a bi eyi ti ṣe ti ẹru-binrin
nipa ti ara: ṣugbọn èyí ti ominira-obin-
rin ni a bi nipa ileri. (Rom 9:7; Gen
18:10; Heb 11:11.)
24. Nkan wọnyìí jẹ́ apẹẹrẹ: nitori pe
awọn obinrin wọnyìí ni majẹmu mejee-
ji; ọkan lati orí òkè Sinai wá, ti a bi
loko-ẹrú, ti i ṣe Hagari. (Deut 33:2.)
25. Nitori Hagari yìí ni oke Sinai
Arabia, ti o si duro fun Jerusalemu ti ó
wà nisinsinyìí, ti o si wà loko-ẹrú pẹlu
awọn ọmọ rẹ̀.
26. Ṣugbọn Jerusalemu ti òkè jẹ́
ominira, eyi ti i ṣe iya wa. (Isa 2:2;
Heb 12:22; Ifh 3:12.)
27. Nitori a ti kọ ọ pe, "Maa yọ̀, iwọ
àgàn ti kò bimọ: bú si ayọ̀ ki o si kigbe
soke, iwọ ti kò rọbí rí; nitori awọn
ọmọ ẹni aláhoro pọ̀ ju ti abilekọ lọ."
(Isa 54:1.)
28. Nję ara, ọmọ ileri ni awa gẹgẹ bi
Isaaki. (A.A. 3:25; Rom 9:8.)
29. Ṣugbọn bi eyi ti a bi nipa ti ara ti
ṣe inunibini nigba naa si eyi ti a bi nipa
ti Ẹ̀mí, bẹẹ si ni ní isinsinyìí. (Gen
21:9.)
30. Ṣugbọn iwe-mimọ ha ti wi? "Lé
ẹru-binrin naa jade ati ọmọ rẹ̀ nitori
ọmọ ẹrubinrin ki yoo ba ọmọ omini-
ra-obinrin jogún pọ̀." (Gen 21:10
–12.)
31. Nitori naa, ará, awa kìí ṣe ọmọ
ẹrúbinrin bikoṣe ti ominira obinrin.

ORI 5.

**Ominira ni a pe yin si.**

NITORI naa ẹ duro ṣinṣin ninu
ominira naa eyi ti Kristi fi sọ wa di
ominira, ki ẹ má sì ṣe tún tẹ ọrùn bọ̀
ajaga ẹrú mọ. (Jhn 8:32; A.A. 15:10.)
2. Kiyesi i, emi Paulu ni o wi fun yin
pé, bi a ba kọ yin nilà, Kristi ki yoo
lérè fun yin ni ohunkohun. (A.A.
15:1.)
3. Mo sì tún sọ fun olukuluku
eniyan ti a kọ ni ilà pe, o di ajigbèsè
lati pa gbogbo òfin mọ́. (Gal 3:10.)
4. A ti yà yin kuro lọdọ Kristi, ẹ̀yin
ti nfẹ́ ki a da yin lare nipa òfin; ẹ ti
ṣubu kuro ninu oore-ọ̀fẹ́. (Heb 12:15;
2 Pet 3:17.)
5. Nitori nipa Ẹ̀mí awa nfi igbagbọ
duro de ireti ododo. (Rom 8:23,24;
2 Tim 4:8.)
6. Nitori ninu Kristi Jesu ìkọlà kò
jẹ ohun kan, tabi aikọlà; ṣugbọn
igbagbọ ti nṣiṣẹ nipa ifẹ. (1 Kor 7:19;
Jms 2:18.)
7. Ẹyin ti nsáré daradara; tani dí yin
lọwọ lati ṣe igbọran si òtítọ́? (1 Kor
9:24; Gal 3:1.)
8. Iyipada yìí kò ti ọdọ ẹni ti o pè yin
wá. (Gal 1:6.)
9. Iwukara kíún ni í mú gbogbo iyẹ-
fun wú. (1 Kor 5:6.)
10. Mo ni igbẹkẹle si yin ninu
Oluwa pe, ẹ̀yin ki yoo ni èrò ohun
miran; ṣugbọn ẹni ti nyọ yin lẹnu yoo
ru idajọ tirẹ̀, ẹnikẹni ti o wù ki o jẹ. (2
Kor 2:3; Gal 1:7.)
11. Ṣugbọn, ará, bi emi bá nwaasu
ikọlà sibẹ, kinni ìdí ti a fi nṣe inunibini
si mi síbẹ̀? Nję ikọsẹ̀ agbelebu ti kuro.
(Gal 4:29; 6:12; 1 Kor 1:23.)

12. Emi iba fẹ́ ki awọn ti nyọ yin lẹnu tilẹ̀ gé ẹya-ara wọn kan kuro.

**Itumọ Ominira.**

13. Nitori a ti pè yin si ominira, ará; kìkì pé ki ẹ má ṣe lo ominira yin bi ànfàní sipa ti ara, ṣugbọn ẹ maa fi ìfẹ́ sin ọmọnikeji yin. (1 Kor 8:9; 1 Pet 2:16; 1 Kor 9:19.)

14. Nitori pe a kó gbogbo ofin ja ninu eyi pe, "Iwọ fẹ́ ọmọnikeji rẹ gẹgẹ bi ara rẹ." (Lef 19:18; Matt 7:12; 22:39; Rom 13:8.)

15. Ṣugbọn bi ẹ̀yín ba nbu ara yin ṣán, ti ẹ si njẹ ara yin run, ẹ kiyesara ki ẹ má ṣe pa ara yin run.

**Rin nipa ti Ẹmi.**

16. Njẹ mo ni, Ẹ maa rin nipa ti Ẹ̀mí, ẹyin ki yoo si mu ifẹkufẹ ti ara ṣẹ. (Rom 8:4; ẹsẹ 24,25; Ef 2:3.)

17. Nitori ti ara nṣe ifẹkufẹ lòdì si Ẹ̀mí, ati Ẹmí lòdì si ara: awọn wọnyìí si lòdì si ara wọn; ki ẹ má baa lè ṣe ohun ti ẹyin nfẹ́. (Rom 7:15–23.)

18. Ṣugbọn bi a ba nti ọwọ́ Ẹmi ṣamọ̀nà yin, ẹyin kò sí labẹ ofin. (Rom 6:14.)

19. Njẹ awọn iṣẹ ti ara farahàn, tii ṣe wọnyìí; panṣaga, àgbèrè, iwa eerí, wọbia, (Ef 5:3; Kol 3:5.)

20. Ibọriṣa, oṣó, irira, ìjà,ìlara,ibinu, asọ̀, ìṣọ̀tẹ̀, àdámọ̀.

21. Àránkan, ìpàniyàn, imutipara, irede-òru, ati irú iwọnyìí; awọn ohun ti mo nwi fun yin tẹ́lẹ̀, gẹgẹ bi mo ti wi fun yin tẹ́lẹ̀ ri pe, awọn ti nṣe nkan báwọ̀nyìí ki yoo jogun ijọba Ọlọrun. (1 Kor 6:9;13: 2.)

22. Ṣugbọn eso ti Ẹmí ni ìfẹ́, ayọ̀, alafia, ipamọra, ìwà pẹ̀lẹ́, iṣoore, ìgbàgbọ́, (Ef 5:9; Kol 3:12–15; 1 Kor 13:7.)

23. Ìwà tutu, ati ikora-ẹni nijanu: òfin kan kò lodi si irú wọ̀nyìí,

24. Awọn ti i ṣe ti Kristi Jesu ti kan ara mọ́ agbelebu pẹlu ifẹ ati ifẹkufẹ rẹ̀. (Rom 6:6.)

**Ọ̀rọ̀-Ìyànjú ati Ìkìlọ̀.**

25. Bi awa ba wà láàyè sipa ti Ẹmí, ẹ jẹ ki a si ma a rìn nipa ti Ẹ̀mí. (Rom 8:4.)

26. Ẹ má ṣe jẹ ki a maa ṣogo-asán, ki a má mu ọmọnikeji wa binú, ki a ma ṣe ilara ọmọnikeji wa. (Filp 2:3.)

ORI 6.

ARÁ, bi a tilẹ mu eniyan ninu iṣubu kan, ki ẹ̀yin ti i ṣe ti Ẹmí mu iru ẹni bẹẹ bọ̀ sípò ninu ẹ̀mí iwa tútù; ki iwọ tikararẹ maa kiyesara, ki a má baa dán ìwọ naa wò pẹlu.

2. Ẹ maa ru ẹrù ọmọnikeji yin, ki ẹ si fi bẹẹ mu ofin Kristi ṣẹ. (Rom 15:1; Jms 2:8.)

3. Nitori bi eniyan kan ba nro ara rẹ̀, si ẹnikan, nigba ti kò jẹ́ nkan, o ntan ara rẹ̀ jẹ. (Rom 12:3; 1 Kor 8:2; 2 Kor 3:5.)

4. Ṣugbọn ki olukuluku yẹ iṣẹ ara rẹ̀ wò, nigba naa, ohun imu-ṣogo rẹ̀ yoo jẹ́ ninu ti ara rẹ̀ nikan, ki yoo si jẹ ninu ti ọmọnikeji rẹ̀. (1 Kor 11:28; Filp 1:26.)

5. Nitori pe olukuluku ni yoo ru ẹrù ara rẹ̀

6. Ṣugbọn ki ẹni ti a nkọ ninu ọ̀rọ̀ naa maa pèsè ohun rere gbogbo fun ẹni ti nkọni. (1 Kor 9:11.)

7. Ki a ma ṣe tàn yin jẹ; a kò lè gan Ọlọrun: nitori ohunkohun ti eniyan bá funrugbìn, oun ni yoo sì ká.

8. Nitori ẹni ti o ba nfunrugbìn sípa ti ara yoo ká idibàjẹ́, ti ara ṣugbọn ẹni ti nfurugbin sipa ti ẹmí yoo ti inú ẹ̀mí ká ìyè àìnipẹkun.

9. Ẹ ma si jẹ ki àárẹ̀-ọkàn mú wa ní ṣiṣe-rere,, nitori ti a o kórè nigba ti àkókò bá dé, bi a kò bá ṣe àárẹ̀. (1 Kor 15:58; Heb 3:6; Ifh 2:10.)

10. Njẹ bi a ti nri àkókò, ẹ jẹ ki a maa ṣoore fun gbogbo eniyan, ati paapaa fun awọn ti i ṣe ara ilé igbagbọ. (Jhn 9:4; Ef 2:19.)

**Ominira ati agbelebu Kristi.**

11. Ẹ wo bi mo ti fi ọwọ́ ara mi kọwe gàdàgbà-gadagba si yin.

12. Iye awọn ti nfẹ ṣe aṣehàn ni ara, wọn nrọ yin lati kọlà; kìkì nitori pe ki

a ma baa ṣe inunibini si wọn nitori agbelebu Kristi. (Matt 23:27,28; A.A. 15:1; Gal 5:11.)

13. Nitori awọn ti a kọ nila paapaa kò pa òfin mọ́, ṣugbọn wọn nfẹ mu yin kọlà, ki wọn lè maa ṣogo ninu ara yin. (Rom 2:25; Filp 3:3.)

14. Ṣugbọn ki a máṣe rii pe emi nṣogo, bikoṣe ninu agbelebu Jesu Kristi Oluwa wa, nipasẹ ẹni ti a ti kan ayé mọ́ agbelebu fun mi, ati emi fun ayé. (Gal 2:20; Rom 6:2,6.)

15. Nitori pe ninu Kristi Jesu Ikọla kò jẹ ohun kan, tabi aikọla, bikoṣe ẹ̀dá tuntun. (2 Kor 5:17.)

16. Ki alaafia ati aanu wà lori gbogbo awọn ti nrin ni ìlànà yii, ati lori Israẹli Ọlọrun.

17. Lati isinsinyìí lọ, ki ẹnikẹni máṣe yọ mi lẹnu mọ́; nitori emi nru àpá Jesu Oluwa kiri ni ara mi. (2 Kor 1:5.)

**Oore-ọfẹ.**

18. Ará, oore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ki o wà pẹlu ẹ̀mí yin. Amin.

49

# AWỌN ARA EFESU

**(A.D. 64)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ikini Paulu.**

PAULU, Aposteli Jesu Kristi nipa ifẹ Ọlọrun, si awọn ènìyàn-mímọ́ ti o wà ni Efesu, ati si awọn onigbagbọ ninu Kristi Jesu: (2 Kor 1:1; 1 Kor 1:1; Kol 1:1,2; Filp 1:1.)

2. Oore-ọfẹ si yin, ati alaafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba wa ati Kristi Oluwa. (Rom 1:7.)

**Ipilẹṣẹ ijọ Ọlọrun ni Efesu.**

3. Olùbùkún ni Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, ẹni ti o ti fi gbogbo ìbùkún ẹmi ninu awọn ọrun bùkún wa ninu Kristi: (2 Kor 1:3; Ef 2:6; 3:10; 6:12.)

4. Ani gẹgẹ bi o ti yàn wa ninu rẹ̀ ṣaaju ipilẹṣẹ ayé, ki awa lè jẹ́ mimọ ati alailabuku niwaju rẹ ninu ifẹ: (Ef 5:27; Kol 1:22; Ef 4:2,15,16.)

5. Ẹni ti o ti yàn wa tẹlẹ si ìsọdọmọ nipa Jesu Kristi fun ara rẹ̀, gẹgẹ bi ìdùnnú ifẹ rẹ̀: (Rom 8:29.)

6. Fun ìyìn ogo oore-ọfẹ rẹ̀, eyi tí ò dà lù wá ninu Ayànfẹ́:

7. Ninu ẹni ti awa ni ìràpadà wa nipa ẹ̀jẹ̀ rẹ̀, ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ wa, gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ oore-ọfẹ rẹ̀: (Kol 1:14.)

8. Eyi ti o sọ di pupọ fun wa ninu gbogbo ọgbọ́n ati òye, (Rom 16:25.)

9. Ẹni ti o ti sọ ohun ijinlẹ ifẹ rẹ̀ di mímọ̀ fun wa, gẹgẹ bi ìdùnnú rẹ̀, eyi ti o ti pinnu ninu rẹ̀,

10. Fun iṣẹ́ ìríjú ti kíkún akókò naa, ki o lè kó ohun gbogbo jọ ninu Kristi, ìbáà ṣe eyi ti nbẹ ninu awọn ọrun, tabi eyi ti nbẹ ni ayé, ani ninu rẹ̀; (Gal 4:4.)

11. Ninu ẹni ti awa ti ri ogún gbà pẹlu, ti a ti pinnu tẹ́lẹ̀ gẹgẹ bi ìmọ̀ ìfẹ́ ẹni naa ti nṣe ohun gbogbo gẹgẹ bi ìmọ̀ ìfẹ́ rẹ̀. (Ef 3:11; Rom 9:17; Heb 6:17.)

12. Ki awa le jẹ fun ìyìn ogo rẹ̀, awa ti a ti ni ireti ṣaaju ninu Kristi; (ẹsẹ 6,14. Kol 1:16,20.)

13. Ninu ẹni ti ẹyin pẹlu, nigba ti ẹyin ti gbọ́ ọ̀rọ̀ otitọ ihinrere ìgbàlà yin, ninu ẹni ti ẹyin ti gbagbọ pẹlu, a fi Ẹmi Mimọ ileri ṣe èdìdí yin, (Kol 1:5; Ef 4:30.)

14. Eyi ti i ṣe ẹ̀rí ìní wa, fun irapada ohun ini Ọlọrun si ìyìn ogo rẹ̀. (2 Kor 1:22; A.A. 20:32.)

**Adura fun awọn ara Efesu.**

15. Nitori èyí, pẹlu, nigba ti mo ti gburo ìgbàgbọ́ ti nbẹ laarin yin ninu Jesu Oluwa, ati ifẹ yin si gbogbo awọn eniyan mimọ. (Kol 1:4; Ef 3:18.)